اتحاد علماء افريقيا
UNION OF AFRICAN MUSLIM SCHOLLARS
UNION DES ULEMAS D'AFRIQUE

# الدروس المهمة لعامة الأمّة

## سماحة الشيخ عبد اللّه بن عبد العزيز بن باز رحمه الله

قام بترجمته إلى اليوروبا

## الأستاذ حبيب اللّه بن عبد الرحمن الأيدوي

# *ÀWỌN ẸKỌ́ PÀTÀKÌ FÚN ỌGỌ̀Ọ̀RỌ̀ ÀWỌN MÙSÙLÙMÍ*

***LÁTI ỌWỌ́:***

**ASH-SHAYKH ‘ABDUL-‘AZĪZ BN ‘ABDILLĀH BN BĀZ**

***ÌTUMỌ̀ SÍ YORÙBÁ:***

***Habībullāh Bn AbdirRahmān Al-Edewī***


طبع على نفقة وصية خولة دخيل الجسار رحمها الله (دولة الكويت) بإشراف اتحاد علماء إفريقيا

**A tẹ̀ ẹ́ jáde pẹ̀lú ìnáwó *Waṣiyyah Khawlah Dakhīl Al-Jassār*, kí Ọlọ́hun kẹ́ ẹ, (Orílẹ̀-Èdè *Kuwait*) ní abẹ́ àmójútó Ìṣọ̀kan àwọn Àlùfáà Áfíríkà**

2016/1437

بسم الله الرحمن الرحيم

(Mo bẹ̀rẹ̀) ní Orúkọ Ọlọ́hun Allāh, Ọba Àjọkẹ́ Ayé, Ọba Àṣàkẹ́ Ọ̀run

**Ọ̀RỌ̀ ÀKỌ́SỌ**

Gbogbo ọpẹ́ àti ẹyìn ti Ọlọ́hun Ọba gbogbo àgbáyé ni í ṣe, àti pé àtubọ̀tán rere ti àwọn olùbẹ̀rù Ọlọ́hun ni í ṣe. Kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá ẹrúsìn Rẹ̀ àti Ìránṣẹ́ Rẹ̀ Ànábì wa Muḥammad, àwọn ará ilé rẹ̀, àti gbogbo àwọn sàábé rẹ̀ pátápátá.

Lẹ́yìn náà, eléyìí ni àwọn ọ̀rọ̀ péréte nípa àlàyé ohun tí ó ṣe ọ̀ranyàn fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ Mùsùlùmi láti mọ̀ nípa ẹ̀sìn *Islām*. Mo sọ ọ́ ní: (**ÀWỌN Ẹ̀KỌ́ PÀTÀKÌ FÚN Ọ̀GỌ̀Ọ̀RỌ̀ ÀWỌN MÙSÙLÙMÍ**).

Mo wá ń bẹ Ọlọ́hun Allāh kí Ó jẹ́ kí ó ṣe àwọn Mùsùlùmi ní àǹfààní, kí Ó sì gbà á (ní ìjọsìn) ní ọwọ́ mi, dájúdájú Òun ni Ọlọ́rẹ, Alápọ̀n-ọ́nlé.

**‘ABDUL-‘AZĪZ BN ‘ABDIL-LĀH BN BĀZ**

## ÀWỌN Ẹ̀KỌ́ PÀTÀKÌ FÚN Ọ̀GỌ̀Ọ̀RỌ̀ ÀWỌN MÙSÙLÙMÍ [1]

**Ẹ̀KỌ́ ÀKỌ́KỌ́:**

(Kíkọ́ wọn ní) *Sūratul-Fātiḥah* àti ohun tí ó bá rọrùn nínú àwọn *Sūrah* kéékèèké láti *Sūratuz-Zalzalah* (*Qur’ān*: 99) dé *Sūratun-Nās*, pẹ̀lú pípè é síwọn lẹ́nu, títún kíké rẹ̀ ṣe, kíkọ́ wọn ní híhá rẹ̀, àti àlàyé ohun tí àgbọ́yé rẹ̀ bá ṣe ọ̀ranyàn.

**Ẹ̀KỌ́ KEJÌ:**

Ìjẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh, àti pé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, pẹ̀lú àtúpalẹ̀ àwọn ìtumọ̀ rẹ̀ àti àlàyé àwọn májẹ̀mu **(*lā ’ilāha ’illā Allāh*)** kò sí ọlọ́hun kan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh, èyí tí ó túmọ̀ sí: (*lā ’ilāha*) “kò sí ọlọ́hun kan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn’’ jẹ́ àtakò sí gbogbo ohun tí à ń jọ́sìn fún lẹ́yìn Ọlọ́hun Allāh, nígbà tì (*’illā Allāh*) “àyàfi Ọlọ́hun Allāh” sì jẹ́ ìfi ìjọsìn rinlẹ̀ fún Ọlọ́hun Allāh nìkan ṣoṣo, kò sí orogún fún Un.

Níti àwọn májẹ̀mu **(*lā ’ilāha ’illā Allāh*)** kò sí ọlọ́hun kan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh, àwọn nìwọ̀nyí: Ìmọ̀, eléyìí tí yóò bi àìmọ̀kan wó. Àmọ̀dájú, eléyìí tí yóò bi iyèméjì wó. Òtítọ́-inú, eléyìí tí yóò bi ẹbọ wó. Òdodo, eléyìí tí yóò bi irọ́ wó. Ìfẹ́, eléyìí tí yóò bi ìkórira wó. Ìjuwọ́-jusẹ̀sílẹ̀, eléyìí tí yóò bi pípatì wó. Ìgbàfà, eléyìí tí yóò bi àtakò wó. Àti ṣíṣe àìgbàgbọ́ sí ohun mìíràn tí à ń sìn lẹ́yìn Ọlọ́hun Allāh.

A sì ti ko wọn (àwọn májẹ̀mu náà) jọ sínú ilé-orin méjì yìí:

> **Ìmọ̀, àmọ̀dájú, àti òtítọ́-inú, àti gbígbà lódodo rẹ pẹ̀lú;**
> **ìfẹ́, ìjuwọ́-jusẹ̀sílẹ̀, àti ìgbàfà fún un.**
> **A ṣe àlékún ìkẹjọ eléyìí tí í ṣe àìgbàgbọ́ rẹ sí**
> **gbogbo ohun mìíràn tí à ń sìn lẹ́yìn Ọlọ́hun Allāh.**

**Ẹ̀KỌ́ KẸTA:**

Àwọn orígun ìgbàgbọ́ òdodo, mẹ́fà ni wọ́n: Kí o gba Ọlọ́hun Allāh gbọ́ lódodo, àwọn *Malā’ikah* Rẹ̀, àwọn tírà Rẹ̀, àwọn Ìránṣẹ́ Rẹ̀ àti ọjọ́ ìkẹyìn, kí o sì gba kádàrá gbọ́, èyí tí ó dára nínú rẹ̀ àti èyí tí kò dára láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun Allāh tí Ọlá Rẹ̀ ga ni ó ti wá.

**Ẹ̀KỌ́ KẸRIN:**

Àlàyé ìpín mímọ Ọlọ́hun lọ́kan (*Tawḥeed*), mẹ́ta ni: ìmú-Ọlọ́hun lọ́kan pẹ̀lú *Rubūbiyyah* (ìfirinlẹ̀ pé Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo ni Olùṣẹ̀dá, Olùdari, Olùsọni di alààyè, Olùpani, Olùpèsè fún àwọn ẹ̀dá àti Alágbára), ìmú-Ọlọ́hun lọ́kan pẹ̀lú *’Ulūhiyyah* (ìmú-Ọlọ́hun lọ́kan pẹ̀lú gbogbo ìran ìjọsìn), àti ìmọ-Ọlọ́hun lọ́kan pẹ̀lú àwọn Orúkọ àti Ìròyìn Rẹ̀.

**Ẹbọ ṣíṣe pín sí mẹ́ta: Ẹbọ tí ó tóbi jùlọ, ẹbọ tí ó kéré jùlọ, àti ẹbọ tí ó pamọ́.**

[1] Àtẹ̀jáde ìwé yìí ti jáde rí papọ̀ mọ́ àwọn ìwé àtẹ̀jáde *Ri’āsah* ní ọdún 1403 A.H., a wá ṣe àlékún sí i nígbà tí àtúntẹ̀ yìí fẹ́ wáyé.

**Ẹbọ tí ó tóbi jùlọ:** Ó máa ń ba iṣẹ́ ẹ̀dá jẹ́, yóò sì sọ wíwọ iná gbére di ọ̀ranyàn lórí ẹni tí ó bá kú sí orí rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga ti sọ wí pé:

> **"Tí ó bá ṣe wípé wọ́n ṣe ẹbọ ni, dájúdájú gbogbo ohun tí wọ́n ń ṣe niṣẹ́ ni kì bá bàjẹ́ fún wọn''.**[2]

Ó (Ọlọ́hun), mímọ́ ni fún Un, tún wí pé:

> **"Kò lẹ́tọ̀ọ́ fún àwọn ọ̀ṣẹbọ láti máa gbé àwọn Mọṣáláṣí Ọlọ́hun ró tí àwọn náà sì jẹ́rìí lórí ẹ̀mí ara wọn pẹ̀lú àìgbàgbọ́. Iṣẹ́ àwọn wọ̀nun ti bàjẹ́, àti pé inú iná ni wọn yóò máa wà lọ gbére''.**[3]

Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá kú sí orí rẹ̀; Ọlọ́hun kò ní ṣe àforíjìn fún un, ọgbà-ìdẹ̀ra (*Al-Jannah*) sì ti di èèwọ̀ fún un, gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun Ọba Abiyì tí Ó gbọngbọ́n ti wí pé:

> **"Dájúdájú Ọlọ́hun kì í ṣe àforíjìn kí á ṣe ẹbọ pẹ̀lú Rẹ̀, ṣùgbọ́n Ó máa ń ṣe àforíjìn ohun tí kò tó eléyìí fún ẹni tí Ó bá fẹ́''.**[4]

Ó (Ọlọ́hun), mímọ́ ni fún Un, tún wí pé:

> **"Dájúdájú ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe ẹbọ pẹ̀lú Ọlọ́hun, dájúdájú Ọlọ́hun ti ṣe ọgbà-ìdẹ̀ra (*Al-Jannah*) ní èèwọ̀ fún un, àti pé iná ni ibùgbé rẹ. Kò sì sí alárànṣe kankan fún àwọn alábòsí''.**[5]

Nínú àwọn ìran rẹ̀ ni pípe àwọn òkú àti àwọn òrìṣà, wíwá ìrànlọ́wọ̀ kúrò nínú ewu pẹ̀lú wọn, jíjẹ́jẹ̀ẹ́ fún wọn, dídú ẹran fún wọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Níti ẹbọ tí ó kéré jùlọ:** Ohun ni ohun tí ó fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ pé Ọlọ́hun nínú tírà Rẹ̀ tàbí Òjíṣẹ́ Rẹ̀ nínú ìlànà (*Sunnah*) rẹ̀ pè é ní ẹbọ ṣùgbọ́n tí kì í ṣe ara ìran ẹbọ tí ó tóbi jùlọ, gẹ́gẹ́ bíi; káríni nínú àwọn iṣẹ́ kan, fífi ohun mìíràn yàtọ̀ sí Ọlọ́hun Allāh búra, gbólóhùn tí Ọlọ́hun bá fẹ́ ti lágbájá náà sì fẹ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nítorí ọ̀rọ̀ Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun - kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- tí ó sọ pé:

> **"Ohun tí ó bani lẹ́rù jùlọ tí mò ń bẹ̀rù fún yín ni ẹbọ tí ó kéré jùlọ''. Wọ́n (àwọn sàábé rẹ̀) bi í léèrè nípa rẹ̀? Ó sì dáhùn pé: "Ohun ni káríni''.**

Imām Aḥmad, *Aṭ-Ṭabarānī* àti *Al-Bayhaqī* ni ó gbà á wá láti ọ̀dọ̀ Maḥmūd ọmọ Labīd *Al-'Anṣārī* –kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i- pẹ̀lú ojúpọ̀nà ẹ̀gbàwá tí ó dára. *Aṭ-Ṭabarānī* tún gbà á wá pẹ̀lú àwọn ojúpọ̀nà ẹ̀gbàwá tí ó dára láti ọ̀dọ̀ Maḥmūd ọmọ Labīd tí ó gbà á wá láti ọ̀dọ̀ Rāfi' ọmọ Khadīj tí òun náà gbà á wá láti ọ̀dọ̀ Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a-. Àti gbólóhùn Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- tí ó sọ pé:

> **"Ẹnikẹ́ni tí ó bá fi ohun tí ó yàtọ̀ sí Ọlọ́hun Allāh búra, dájúdájú onítọ̀hún ti ṣẹbọ''.**

[2] *Al–'An'ām*: 88.
[3] *At-Tawbah*: 17.
[4] *An-Nisā'*: 48.
[5] *Al-Mā'idah*: 72.

Imām Aḥmad ni ó gbà á wá pẹ̀lú ojúpọ̀nà ẹ̀gbàwá tí ó ní àláàfíà láti ọ̀dọ̀ ‘Umar ọmọ Al-Khaṭṭāb -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i-. Abū Dāwūd àti At-Tirmidhī náà gbà á wá pẹ̀lú ojúpọ̀nà ẹ̀gbàwá tí ó ní àlááfíà láti ọ̀dọ̀ ọmọ ‘Umar -kí Ọlọ́hun yọ́nú sí àwọn méjèèjì- tí òun náà ń gbà á wá láti ọ̀dọ̀ Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- pé ó sọ pé:

> **"Ẹnikẹ́ni tí ó bá búra pẹ̀lú ohun tí ó yàtọ̀ sí Ọlọ́hun Allāh, dájúdájú onítọ̀hún ti ṣe àìgbàgbọ́ tàbí ó ṣẹbọ''.**

Àti gbólóhùn Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- tí ó sọ pé:

> **"Ẹ má ṣe máa sọ pé; tí Ọlọ́hun bá fẹ́ ti lágbájá sì fẹ́, ṣùgbọ́n ẹ́ máa sọ pé; tí Ọlọ́hun bá fẹ́ lẹ́yìn náà ti lágbájá sì fẹ́''.**

Abū Dāwūd ni ó gbà á wá pẹ̀lú ojúpọ̀nà ẹ̀gbàwá tí ó ní àlááfíà láti ọ̀dọ̀ Ḥudhayfah ọmọ Al-Yamān -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i-. Ìran ẹbọ yìí kì í yọ ènìyàn kúrò nínú ẹ̀sìn *Islām*; kì í sì í sọ wíwọ iná gbére di ọ̀ranyàn lórí ẹ̀rú, ṣùgbọ́n ó tako ìmọ-Ọlọ́hun lọ́kan tí ó pé eléyìí tí ó ṣe ọ̀ranyàn lórí Mùsùlùmí.
Níti ìran kẹta; eléyìí tí i ṣe ẹbọ tí ó pamọ́, ẹ̀rí rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- tí ó sọ pé:

> **"Ṣé kí n fún yín nì ìró nípa ohun tí ń bàmí lẹ́rù fún yín jù *Al-Masīḥ* èké lọ?'' Wọ́n (àwọn sàábé) wí pé: Bẹ́ẹ̀ni irẹ̀ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun. Ó wí pé: " Ẹbọ tí ó pamọ́ ni...tí ènìyàn yóò dìde kírun, tí yóò máa ṣe ìrun rẹ̀ ní ọ̀ṣọ́ nítorí pé ó ríi pé àwọn ènìyàn ń wo òun''.**

Imām Aḥmad ni ó gbà á wá nínú tírà *Musnad* rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ Abū Sa‘īd *Al-Khudrī* -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i-.
A sì tún le pín ẹbọ sí méjì péré: Ẹbọ tí ó tóbi jùlọ àti ẹbọ tí ó kéré jùlọ. Nígbà náá ẹbọ tí ó pamọ́ yóò kó àwọn méjèèjì sínú. Ó (ẹbọ tí ó pamọ́) le wà nínú ẹbọ tí ó tóbi jùlọ gẹ́gẹ́ bíi ẹbọ àwọn alágàbàgebè. Nítorí pé wọ́n máa ń fi àdìsọ́kàn burúkú wọn pamọ́, wọn yóò sì máa pirọrọ bíi Mùsùlùmì níti káríni àti nítorí pé wọn ń bẹ̀rù fún ẹ̀mí ara wọn.
Ó sì tún le wà nínú ẹbọ tí ó kéré jùlọ bíi káríni, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú ẹ̀gbàwá *Ḥadīth* tí Maḥmūd ọmọ Labīd *Al-'Anṣārī* gbà wá tí ó ti siwájú, àti ẹ̀gbàwá *Ḥadīth* Abī Sa‘īd *Al-Khudrī* tí a ti sọ tẹ́lẹ̀... Àti pé Ọwọ́ Ọlọ́hun Allāh ni kòngẹ́ wà.

**ẸKỌ́ KARÙN-ÚN:** ÀWỌN ORÍGUN ẸSÌN *ISLĀM*, MÁRÙN-ÚN NI WỌ́N:

Ìjẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan, àti pé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Rẹ̀, gbígbé ìrun dúró, yíyọ *Zakāh*, gbígba ààwẹ̀ *Ramaḍān*, ṣíṣe ìrìn-àjò lọ sí ilé Ọlọ́hun abọ̀wọ̀ fún ẹni tí ó bá ní agbára láti lọ síbẹ̀.

**ẸKỌ́ KẸFÀ:** ÀWỌN MÁJẸ̀MU ÌRUN, MẸ́SÀN-ÁN NI WỌ́N:

Ẹ̀sìn *Islām*, làákàyè, líle ṣàdáyanrí, gbígbé ẹ̀gbin kúrò lára, yíyọ ẹ̀gbin kúrò (lára aṣọ, ara àti ààyè ìkìrun), bíbo ìhòhò, wíwọlé àsìkò ìrun, dída ojú kọ gábàsì àti àníyàn.

**ẸKỌ́ KEJE:** ÀWỌN ORÍGUN ÌRUN, MẸ́RÌNLÁ NI WỌ́N:

Dídìde dúró fún ẹni tí ó lágbára, ìgbé Ọlọ́hun tóbi àkọ́kọ́, kíké *Fātiḥah*, rúkúù (títẹ̀ kọ̀kọ̀rọ̀), dídìde nàró déédé lẹ́yìn rúkúù, fífi orí kanlẹ̀ lórí àwọn oríkèé méjèèje, jíjókòó láàrin ìforíkanlẹ̀ méjèèjì, fífi ara balẹ̀ lórí gbogbo iṣẹ́ ìrun, títo àwọn orígun ìrun tẹ̀lé ara wọn, àtáàyá ìgbẹ̀yìn, jíjókòó fún un, ṣíṣe àsàlátú fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a-, àti sálámà méjèèjì.

**ẸKỌ́ KEJỌ:** ÀWỌN Ọ̀RANYÀN ÌRUN, MẸ́JỌ NI WỌ́N:

Gbogbo ìgbé-Ọlọ́hun tóbi yàtọ̀ sí ìgbé-Ọlọ́hun tóbi àkọ́kọ́, gbólóhùn ***sami‘a Allāhu liman ḥamidah*** (Ọlọ́hun máa ń gba ìpè ẹni tí ń yìn Ín) fún *Imām* àti ẹni tí ń dá ìrun kí,

gbólóhùn ***Rabbanā walakal-ḥamd*** (Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba wa! Gbogbo ọpẹ́ àti ẹyìn tì Ẹ ni í ṣe) fún gbogbo akírun, gbólóhùn ***subḥāna Rabbiyal-'Aẓīm*** (mímọ́ ni fún Ọlọ́hun Ọba mi, Ọba tí Ó tóbi) ní rúkúù, gbólóhùn ***subḥaana Rabbiyal-'A'lā*** (mímọ́ ni fún Ọlọ́hun Ọba mi, Ọba tí Ó ga jùlọ) ní ìforíkanlẹ̀, gbólóhùn ***Rabbighfir lī*** (Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba mi! Forí jì mí) láàrin ìforíkanlẹ̀ méjèèji, àtáàyá àkọ́kọ́, àti jíjókòó fún un.

**ÈKỌ́ KẸSÀN-ÁN:** ÀLÀYÉ ÀTÁÁYÁ:

***At-taḥiyyātu lillāhi waṣ-ṣalawātu waṭ-ṭayyibāt, as-salāmu 'alayka 'ayyuhan-nabiyyu waraḥmatullāhi wabarakātuh, as-salāmu 'alaynā wa'alā 'ibādillāhiṣ-ṣāliheen. 'Ashhadu 'an lā 'ilāha 'illallāh, wa'ashhadu 'anna Muḥammadan 'abduhu warasūluh.***

**Gbogbo kíkí ti Ọlọ́hun ni í ṣe, àti gbogbo ìrun àti gbogbo dáadáa. Àlááfíà Ọlọ́hun kí ó máa bá ọ, ìrẹ Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun, àti ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ìbùkún Rẹ̀. Àlááfíà Ọlọ́hun kí ó máa bá wa, kí ó sì máa bá àwọn ẹni dáadáa nínú àwọn ẹrúsìn Ọlọ́hun. Mo jẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan, mo sì jẹ́rìí pé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ ẹrúsìn Rẹ̀ àti Ìránṣẹ́ Rẹ̀.**

Lẹ́yìn náà yóò ṣe àsàlátú fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a-, yóò sì tún tọrọ ìbùkún Ọlọ́hun fún un, yóò sì wí pé:

***Allāhumma ṣalli 'alā Muḥammad, wa'alā 'āli Muḥammad, kamā ṣallayta 'alā Ibrāhīma wa'alā 'āli Ibrāhīm, 'innaka Ḥameedun Majeed, Allāhumma bārik 'alā Muhammad, wa'alā 'āli Muḥammad, kamā bārakta 'alā Ibrāhīma wa'alā 'āli Ibrāhīm, 'innaka Ḥamīdun Majīd.***

**Ìrẹ Ọlọ́hun! Ṣe ìkẹ́ fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad àti fún àwọn ará ilé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad gẹ́gẹ́ bí O ti ṣe ìkẹ́ fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm àti fún àwọn ará ilé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm. Dájúdájú Ìwọ ni Ẹni ẹyìn, Ẹni títóbi. Ìrẹ Ọlọ́hun! Ṣe ìbùkún fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad àti fún àwọn ará ilé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad gẹ́gẹ́ bí O ti ṣe ìbùkún fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm àti fún àwọn ará ilé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm. Dájúdájú Ìwọ ni Ẹni ẹyìn, Ẹni títóbi.**

Lẹ́yìn náà yóò wá ìṣọ́ pẹ̀lú Ọlọ́hun níbi àtáàyá ìgbẹ̀yìn kúrò níbi ìyà inú sàréè, àti kúrò níbi ìyà iná *Jahannam*, àti kúrò níbi wàhálà ìṣẹ̀mí àti ikú, àti kúrò níbi aburú wàhálà *Al-Masīḥ* èké. Lẹ́yìn náà yóò ṣe àṣàyàn àdúà tí ó bá fẹ́; pàápàá jùlọ àwọn àdúà tí ẹ̀gbàwà wà fún, nínú rẹ̀ ni:

***Allāhumma 'a'innī 'alā dhikrik, washukrik, waḥusni 'ibādatik.***

**Ìrẹ Ọlọ́hun! Ràn mí lọ́wọ́ láti máa rántí Rẹ, àti láti máa dúpẹ́ fún Ọ, àti láti máa sìn Ọ́ dáadáa**

***Allāhumma 'innī ẓalamtu nafsī ẓulman kathīran, walā yaghfirudh-dhunūba 'illā 'Ant, faghfir lī***

***maghfiratan min ‘indika warḥamnī, ’innaka ’Antal-Ghafūrur-Raḥīm.***

**Ìrẹ Ọlọ́hun! Dájúdájú èmi ṣe àbòsí fún ẹ̀mí ara mi ní àbòsí tí ó pọ̀, ẹníkan kò sì le ṣe àforíjì ẹ̀ṣẹ̀ àyàfi Ìwọ nìkan. Nítorí náà ṣe àforíjì fún mi láti ọ̀dọ̀ Rẹ, sì tún kẹ́ mi. Dájúdájú Ìwọ gan-an ni Ọlọ́pọ̀lọpọ̀ àforíjì, Ọlọ́pọ̀lọpọ̀ àánú.**

Ṣùgbọ́n níbi àtáàyá alákọ̀kọ́ọ́, yóò dìde lẹ́yìn ijẹ́rìí méjèèjì (láìṣe àsàlátú tàbí àdúà) lọ sí òpó ìrun *(Rak‘ah)* kẹta níbi ìrun Àhílà, Àlàásàré, *Maghrib* àti *‘Ishā’*, tí ó bá sì tún ṣe àsàlátú fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun, ìyẹn ni ó lọ́lá jùlọ nítorí àìṣàdáyanrí àwọn ẹ̀gbàwà tó wá lórí rẹ̀. Lẹ́yìn náà yóò dìde lọ sí òpó ìrun *(Rak‘ah)* kẹta.

**<u>Ẹ̀KỌ́ KẸWÀÁ:</u>** ÀWỌN OHUN TÍ A FẸ́ LÓRÍ ÌRUN, NÍNÚ RẸ̀ NI:

1- Àdúà ìbẹ̀rẹ̀ ìrun.
2- Gbígbé àtẹ́lẹwọ́ ọ̀tún lé ẹ̀yìn àtẹ́lẹwọ́ òsì ní orí àyà ní ìdúró lórí ìrun.
3- Gbígbé ọwọ́ méjèèjì sókè láìya àwọn ọmọ-ìka kàtàkàtà pẹ̀lú nínàró wọn, sí déédé èjìká méjèèjì tàbí etí méjèèjì nígbà tí a bá ṣe ìgbé-Ọlọ́hun tóbi àkọ́kọ́, nígbà tí a bá fẹ́ rúkúù (títẹ̀ kọ̀kọ̀rọ̀), àti nígbà tí a bá fẹ́ nàró dìde déédé lẹ́yìn rúkúù, àti nígbà tí a bá fẹ́ nàró níbi àtáàyá alákọ̀kọ́ọ́ lọ sí òpó ìrun (*Rak‘ah)* kẹta.
4- Ohun tí ó bá lé lórí ẹyọkan nínú ṣíṣe àfọ̀mọ́ fún Ọlọ́hun ní rúkúù àti ìforíkanlẹ̀.
5- Ohun tí ó bá lé lórí ẹyọkan nínú ìtọrọ àforíjì Ọlọ́hun láàrin ìforíkanlẹ̀ méjèèjì.
6- Jíjẹ́ kí orí bá ẹ̀yìn dọ́gba ní rúkúù.
7- Gbígbé pọọlọ apá méjèèjì jìnnà sí ẹ̀gbẹ́ méjèèjì àti ikùn jìnnà sí itan méjèèjì ní ìforíkanlẹ̀.
8- Gbígbé ìgbọ̀nwọ́ méjèèjì kúrò lórí ilẹ̀ nígbà ìforíkanlẹ̀.
9- Kí olùkírun jókòó sí ori àtẹ́lẹsẹ̀ rẹ̀ òsì, kí ó sì nàró àtẹ́lẹsẹ̀ ọ̀tún níbi àtáàyá alákọ̀kọ́ọ́ àti láàrin ìforíkanlẹ̀ méjèèjì.
10- Fífi ìdí lélẹ̀ pẹ̀lú títi ẹsẹ̀ òsì bọ abẹ́ ẹsẹ̀ ọ̀tún tí a ó sì nàró àtẹ́lẹsẹ̀ rẹ̀ níbi àtáàyá ìgbẹ̀yìn.
11- Nínàró ẹsẹ̀ ọ̀tún nígbà ìjòkó.
12- Ṣíṣe àsàlátú àti títọrọ ìbùkún fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad àti àwọn ará ilé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad àti fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm àti àwọn ará ilé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm níbi àtáàyá alákọ̀kọ́ọ́.
13- Ṣíṣe àdúà níbi àtáàyá ìgbẹ̀yìn.

14- Kíkéwú sókè níbi ìrun Àsùnbáà, ìrun Jímọ̀h, ìrun ọdún méjèèjì, ìrun ìwá-omi, àti òpó-ìrun méjì àkọ̀kọ́ọ̀ níbi ìrun *Maghrib* àti *'Ishā'*.

15- Kíkéwú jẹ́jẹ́ níbi ìrun Àhílà àti Àlàásàré àti níbi òpó-ìrun kẹta níbi ìrun *Maghrib* àti òpó-ìrun méjèèjì tí ó gbẹ̀yìn níbi ìrun *'Ishā'*.

16- Kíké ohun mìíràn nínú *Al-Qur'ān* lẹ́yìn *Fātiḥah,* pẹ̀lú àmójútó àwọn iṣẹ́ àṣegbọrẹ mìíràn lórí ìrun tí a ò mẹ́nu bá níbí yìí. Nínú eléyìí ni, ohun tí ó bá lékún lórí gbólóhùn akírun: *Rabbanā walakal-ḥamd* (Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba wa! Gbogbo ọpẹ́ àti ẹyìn tì Ẹ ni í ṣe) lẹ́yìn dídìde nàró láti rúkúù fún *Imām,* ẹni tí ń kírun lẹ́yìn rẹ̀ àti ẹni tí ń dá ìrun kí, ohun tí a fẹ́ lórí ìrun ni. Nínú rẹ̀ bákan náà ni gbígbé ọwọ́ méjèèjì lórí orúnkún méjèèjì pẹ̀lú yíya àwọn ọmọ-ìka ọwọ́ ní rúkúù.

**<u>ÈKỌ́ KỌKÀNLÁ:</u>** ÀWỌN OHUN TÍ Ó MÁA Ń BA ÌRUN JẸ́, MẸ́JỌ NI WỌ́N:

1- Mímọ̀ọ́mọ̀ sọ̀rọ̀ (lórí ìrun) pẹ̀lú ìrántí àti ìmọ̀; ṣùgbọ́n ẹni tí ó gbàgbé àti aláìmọ̀kan, ìyẹn kò le ba ìrun rẹ̀ jẹ́.
2- Ẹ̀rín.
3- Jíjẹun (lórí ìrun).
4- Mímu nǹkan (lórí ìrun).
5- Ṣíṣí ìhòhò sílẹ̀.
6- Yíyẹ̀ púpọ̀ kúrò ní gábàsì.
7- Fífi nǹkan ṣeré lọ́pọ̀lọpọ̀ tẹ̀lé ara wọn lórí ìrun.
8- Kì ìmọ́ra bàjẹ́.

**<u>ÈKỌ́ KEJÌLÁ:</u>** ÀWỌN MÁJẸ̀MU ÀLÙWÀLÁ, MẸ́WÀÁ NI WỌ́N:

Ẹ̀sìn *Islām,* làákàyè, líle ṣàdáyanrí, àníyàn, àti fífi ìdájọ́ rẹ̀ sọ́kàn pẹ̀lú pé kí ó má ní àníyàn láti já a títí tí yóò fi parí ìmọ́ra rẹ̀, kí ó má sí ohun tí ó máa ń sọ àlùwàlá di ọ̀ranyàn lára rẹ̀, fífi omi tàbí òkúta táábà síwájú rẹ̀, mímọ́ omi àti lílẹ́tọ̀ọ́ rẹ̀, fífọ ohun tí kò ní jẹ́ kí omi dé ara dànù, àti wíwọlé àsìkò fún ẹni tí ẹ̀gbin rẹ̀ kì í mọ́wọ́ dúró.

**<u>ÈKỌ́ KẸTÀLÁ:</u>** ÀWỌN Ọ̀RANYÀN ÀLÙWÀLÁ, MẸ́FÀ NI WỌ́N:

Fífọ ojú; nínú rẹ̀ sì ni yíyọ ẹnu àti fífín imú, fífọ ọwọ́ méjèèjì pẹ̀lú ìgúnpá, pípá gbogbo orí; nínú rẹ̀ sì ni etí méjèèjì, fífọ ẹsẹ̀ méjèèjì pẹ̀lú kókósẹ̀, títò ó tẹ̀lé ara wọn àti ṣíṣe é ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé. A sì fẹ́ pípààrà fífọ ojú, ọwọ́ méjèèjì àti ẹsẹ̀ méjèèjì ní ẹ̀ẹ̀mẹta. Bẹ́ẹ̀ náà ni yíyọ ẹnu àti fífín imú. Ṣùgbọ́n ẹ̀ẹ̀kan péré nínú rẹ̀ ni ó ṣe ọ̀ranyàn. Níti orí pípá, a kò fẹ́ pípààrà rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹ̀gbàwá tó ní àláàfíà ṣe tọ́ka sí eléyìí.

**<u>ÈKỌ́ KẸRÌNLÁ:</u>** ÀWỌN OHUN TÍ Ó MÁA Ń BA ÀLÙWÀLÁ JẸ́, MẸ́FÀ NI WỌ́N:

Ohun tí ń jáde láti ọ̀nà méjèèjì (ìdí àti ojú-ara), ohun tí ń jáde láti ara tí ó pọ̀, tí ó sì jẹ́ ẹ̀gbin, yíyẹ̀ làákàyè pẹ̀lú oorun àti ohun tí ó jọ ọ́, fífi ọwọ́ kan abẹ́ bóyá ojú-ara ni tàbí ìdí láìsí gàgá kankan, jíjẹ ẹran ràkúnmí, àti kíkómọ̀ kúrò nínú ẹ̀sìn *Islām,* kí Ọlọ́hun ṣọ́ wa àti gbogbo Mùsùlùmí kúrò níbẹ̀.

**<u>ÀKÍYÈSÍ PÀTÀKÌ:</u>** Níti wíwẹ òkú; ohun tí ó ní àláàfíà ni pé kò já àlùwàlá, eléyìí ni ọ̀rọ̀ àwọn tó pọ̀ jùlọ nínú àwọn onímímọ̀ nítorí pé kò sí ẹ̀rí fún un. Ṣùgbọ́n tí ọwọ́ awẹ̀kú bá kan abẹ́ òkú láìsí gàgá kankan, àlùwàlá ti di ọ̀ranyàn lórí rẹ̀. Ohun tí ó ṣe ọ̀ranyàn ni pé kò gbọdọ̀ fi ọwọ́ kan abẹ́ òkú àyàfi láti ẹ̀yìn gàgá.

Bẹ́ẹ̀ náà ni gbígbá obìnrin mú; kò já àlùwàlá ní ọ̀nà-kọnà, bóyá pẹ̀lú adùn ni tàbí láìsí adùn, èyí ni ó ní àláàfíà jùlọ nínú ọ̀rọ̀ méjì tí àwọn onímímọ̀ sọ nípa rẹ̀ ní òpin ìgbà tí nǹkankan kò bá ti jáde lara rẹ̀. Nítorí pé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a- fi ẹnu ko ẹnu ọ̀kan nínú àwọn ìyàwó rẹ̀, lẹ́yìn náà ó kírun, kò sì ṣe àlùwàlá.
Níti ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun -mímọ́ ni fún Un- nínú (*Sūrah*) *An-Nisā'* àti *Al-Mā'idah*:

**"Tàbí ẹ súnmọ́ àwọn obìnrin''.**[6]

Ohun tí a gbà lérò pẹ̀lú rẹ̀ ni ìbálòpọ̀, èyí ni ó ní àláàfíà jùlọ nínú ọ̀rọ̀ méjì tí àwọn onímímọ̀ sọ nípa rẹ̀. Ohun náà sì ni ọ̀rọ̀ ọmọ 'Abbās -kí Ọlọ́hun yọ́nú sí àwọn méjèèjì-; àti àwọn kan nínú àwọn ẹni ìsiwájú àti àwọn ẹni ìkẹyìn... Àti pé Ọwọ́ Ọlọ́hun Allāh ni kòǹgẹ́ wà.

**<u>Ẹ̀KỌ́ KẸ̀Ẹ̀DÓGÚN:</u>**

Ṣíṣọ̀ṣọ́ pẹ̀lú àwọn ìwà tó bá ofín Ọlọ́hun mu fún gbogbo Mùsùlùmí; nínú rẹ̀ ni: Òdodo, àfọkàntán, àmójúnù, ìtìjú, akin, ọrẹ títa, pípé àdéhùn, bíbọ́wọ́-bọ́sẹ̀ kúrò níbi gbogbo ohun tí Ọlọ́hun ṣe ní èèwọ̀, ṣíṣe dáradára sí alábágbé, ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn aláìní bí agbára bá ti mọ, àti àwọn ìwà mìíràn tí Tírà Ọlọ́hun àti ìlànà Òjíṣẹ́ Rẹ̀ tọ́ka sí bíbá ofín Ọlọ́hun mu rẹ̀.

**<u>Ẹ̀KỌ́ KẸRÌNDÍNLÓGÚN:</u>**

Mímú àwọn ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn *Islām* lò; nínú rẹ̀ ni: Sísálámà, tútújúká, fífi ọwọ́ ọ̀tún jẹun, fífi í mumi, dídá Orúkọ Ọlọ́hun ní ìbẹ̀rẹ̀, ṣíṣe ẹyìn fún Ọlọ́hun ní ìparí, ṣíṣe ẹyìn fún Ọlọ́hun lẹ́yìn sísín, kíkí ẹni tí ó sín tí ó bá ti ṣe ẹyìn fún Ọlọ́hun. Bíbẹ aláìsàn wò, títẹ̀lé òkú (Mùsùlùmí) láti kírun sí i lára àti láti sin ín. Àti àwọn ẹ̀kọ́ tó bá ofín Ọlọ́hun mu nígbà tí a bá fẹ́ wọ Mọ̀ṣáláṣí tàbí ilé àti nígbà tí a bá fẹ́ jáde kúrò nínú àwọn méjèèjì, nígbà tí a bá fẹ́ ṣe ìrìn-àjò, pẹ̀lú àwọn òbí méjèèjì, àwọn alásúnmọ́, àwọn alábágbé, àwọn àgbàlagbà, àwọn ọmọdé, kíkí ẹni tí ó bímọ kú orí ire ọmọ titun, títọrọ àlúbáríkà fún ọkọ àti ìyàwó titun, ìbánikẹ́dùn nígbà àdánwò, àti àwọn ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn *Islām* mìíràn nípa wíwọ aṣọ, bíbọ́ ọ àti wíwọ bàtà.

**<u>Ẹ̀KỌ́ KẸTÀDÍNLÓGÚN:</u>**

Ìkìlọ̀ nípa ẹbọ àti gbogbo ìran ẹ̀ṣẹ̀, nínú rẹ̀ ni: Àwọn ẹ̀ṣẹ̀ méje tí wọ́n máa ń fa ìparun (wọ́n máa ń kó ìparun bà ẹ̀dá). Àwọn náà ni; ẹbọ, idán, pípa ẹ̀mí eléyìí tí Ọlọ́hun ṣe ní èèwọ̀ àyàfi tí ó bá jẹ̀bi ikú, jíjẹ owó ọmọ-òrukàn, jíjẹ owó-èlé, yíyí ẹ̀yìn padà (sísá fún ọ̀tá) ní ojú-ogun ẹ̀sìn, fífi ẹ̀sùn panṣágà kan àwọn obinrin ọmọlabí olùkójúró, aláìmọwọ́-mẹsẹ̀, olùgbàgbọ́ òdodo.

Nínú rẹ̀ tún ni: Ṣíṣe àwọn òbí méjèèjì, jíjá okùn ẹbí, jíjẹ́rìí èké, ìbúra irọ́, fífi sùtá kan alábágbé, ṣíṣe àbòsí fún àwọn ènìyàn níbi ẹ̀jẹ̀, dúkìà àti ọmọlabi wọn àti àwọn ohun mìíràn tí Ọlọ́hun tàbí Ìránṣẹ́ Rẹ̀ -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- kọ̀ nípa rẹ̀.

**<u>Ẹ̀KỌ́ KEJÌDÍNLÓGÚN:</u>**

6 *Sūratun-Nisā'*: 43 àti *Sūratul-Mā'idah*: 6.

Pípalẹ̀ òkú mọ́ àti kíkírun sí i lára, àlàyé rẹ̀ nì yìí:

**Pípalẹ̀ òkú mọ́:**

1- Tí ikú rẹ̀ bá ti dá wa lójú; a ó pa ojú rẹ̀ méjèèjì dé, a ó sì kó irungbọ̀n rẹ̀ jọ.

2- Ọ̀ranyàn ni kí á wẹ̀ òkú Mùsùlùmí àyàfi tí ó bá jẹ́ pé ojú ogun ẹ̀sìn ni ó kú sí. Nígbà náà a kò ní wẹ̀ ẹ́, a kò sì ní kírun sí i lára. Ṣùgbọ́n a ó sin ín pẹ̀lú aṣọ rẹ̀ tí ó kú sí, nítorí pé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- kò wẹ àwọn tí wọ́n kú sí ogun *'Uḥd* kò sì kírun sí wọn lára.

3- Bí a ti máa ń wẹ òkú ni pé kí á bo ìhòhò rẹ̀, lẹ́yìn náà a ó gbé e sí òkè díẹ̀, a ó sì rọra tẹ ikùn rẹ̀ pẹ̀lú pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́. Lẹ́yìn náà awẹ̀kú yóò wọ ìbọ̀wọ́ aláṣọ tàbí ohun tí ó jọ ọ́ yóò sì fi táábà fún un. Lẹ́yìn náà yóò ṣe àlùwàlú tí a máa ń ṣe fún ìrun fún un. Lẹ́yìn náà yóò fọ orí rẹ̀ àti irungbọ̀n rẹ̀ pẹ̀lú omi àti ewé sídírú tàbí ohun tí ó jọ ọ́. Lẹ́yìn náà yóò wẹ ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ ọ̀tún, lẹ́yìn náà yóò wẹ ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ òsì. Lẹ́yìn náà yóò wẹ̀ ẹ́ bẹ́ẹ̀ ní ẹ̀ẹ̀kejì àti ẹ̀ẹ̀kẹta. Gbogbo ìgbà yìí ni yóò máa rọra tẹ ikùn rẹ̀, tí nǹkankan bá jáje lára rẹ̀ yóò fọ̀ ọ́, yóò sì fi òwú tàbì ohun tí ó jọ ọ́ dí ààyè náà. Tí kò bá wá mú ọwọ́ dúró yóò lo amọ̀ gbígbóná tàbí àwọn ohun èlò ìtọ́jú ayé òde-òní bíi pílásítà tàbì ohun tí ó jọ ọ́.

Yóò sì tún àlùwàlú ṣe fún un. Tí kò bá mọ́ pẹ̀lú ẹ̀ẹ̀kẹta, a ó fi kún un títí yóò fi pé ẹ̀ẹ̀marùn-ún tàbí pé ẹ̀ẹ̀mẹje. Lẹ́yìn náà yóò nura fún un, yóò fi lọ́fíndà sí àwọn burè rẹ̀ àti àwọn ààyè ìforíkanlẹ̀ rẹ̀. Ṣùgbọ́n ó dára tí ó bá le fi tùràré sí gbogbo ara rẹ̀, yóò sì tún fi tùràré sí aṣọ tí wọn yóò fi sin ín. Tí túbọ̀mú rẹ̀ tàbí èékánná rẹ̀ bá gùn, yóò dín in kù. Kò ní ya irun rẹ̀. A ó di irun obìnrin sí mẹ́ta, a ó sì dà á sí ẹ̀yìn rẹ̀.

4- Dída aṣọ bo òkú; ohun tí ó ní ọlá jùlọ ni kí á fi aṣọ funfun mẹ́ta sin ọkùnrin, kò ní sí ẹ̀wù tàbí láwàní níbẹ̀, a ó rọra gbé e sínú rẹ̀. Tí a bá sì fi ẹ̀wù; ìró àti ìbora bò ó, kò sí ohun tí ó burú níbẹ̀. Aṣọ márùn-ún ni a sì máa fi ń sin obìnrin: Ẹ̀wù gígùn, ìbòrí, ìró àti ìbora méjì.

Aṣọ kan sí mẹ́ta ni a fi máa ń sin ọmọdé ọkùnrin, a sì máa ń fi ẹ̀wù kan àti ìbora méjì sin ọmọdé obìnrin. Ohun tí ó ṣe ọ̀ranyàn fún gbogbo òkú ni aṣọ kan tí yóò bò gbogbo ara rẹ̀.

Ṣùgbọ́n tí òkú bá wà nínú aṣọ háràmí nígbà tí ó kú; a ó wẹ̀ ẹ́ pẹ̀lú omi àti ewé sídírú, a ó sì sin ín pẹ̀lú ìró rẹ̀ àti kaba rẹ̀ tàbí aṣọ mìíràn. A kò ní bo orí rẹ̀, a kò sì ní bo ojú rẹ̀, a kò sì ní fi lọ́fíndà sí ara rẹ̀, nítorí pé a ó gbé e dìde ní ọjọ́ ìgbéǹde ní ẹni tí ń fọn rere ìjẹ́pè Ọlọ́hun gẹ́gẹ́ bí ẹ̀gbàwá *Ḥadīth* tí ó ní àláàfíà láti ọ̀dọ̀ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- ṣe tọ́ka sí eléyìí. Tí ó

bá ṣe pé òkú tí ó wà nínú aṣọ háràmí nígbà tí ó kú jẹ́ obìnrin; a ó sin ín bí a ó ti sin ẹlòmíràn yàtọ̀ sí i. Ṣùgbọ́n a kò ní fi lọ́fíndà sí ara rẹ̀, a kò sì ní fi ìbòjú bo ojú rẹ̀, a kò sì ní fi ìbọ̀wọ́ bọ ọwọ́ rẹ̀ méjèèjì. Aṣọ tí a ó fi sin ín ni a ó fi bo ojú rẹ̀ àti ọwọ́ rẹ̀ méjèèjì gẹ́gẹ́ bí àlàyé bí a ti ṣe máa ń da aṣọ bo òkú obìnrin tí ó ti siwájú.

5- Ẹni tí ó ní ẹ̀tọ́ jùlọ láti wẹ̀ ẹ́, kírun sí i lára àti láti sin ín ni ẹni tí ó bá sọ àsọtẹ́lẹ̀ bẹ́ẹ̀ fun. Lẹ́yìn náà bàbá, baba-bàbá, lẹ́yìn náà bí àwọn akógúntán rẹ̀ bá ṣe súnmọ́n ọn sí.

Ẹni tí ó ní ẹ̀tọ́ jùlọ láti wẹ̀ obìnrin ni ẹni tí ó bá sọ àsọtẹ́lẹ̀ bẹ́ẹ̀ fun. Lẹ́yìn náà ìyá, lẹ́yìn náà ìyáa-ìyá, lẹ́yìn náà bí àwọn alásúnmọ́n rẹ̀ obìnrin bá ṣe súnmọ́n ọn sí. Ó sì lẹ́tọ̀ọ́ fún ọkọ àti ìyàwó kí ọ̀kan nínú wọn wẹ ìkejì, nítorí pé (Abū Bakr) olódodo -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i- ìyàwó rẹ̀ ni ó wẹ̀ ẹ́. Àti pé ‘Aliyy -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i- náà wẹ̀ ìyàwó rẹ̀ Fāṭimah -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí i-.

6- Ìròyìn kíkí ìrun sí òkú lára: (Ẹni tí ó ń kírun sí i lára) yóò gbé Ọlọ́hun tóbi ní ẹ̀ẹ̀mẹrin, yóò sì ké *Fātiḥah* lẹ́yìn àkọ́kọ́. Ó sì dára tí ó bá le ké ọgbà-ọ̀rọ̀ (*Sūrah*) kékeré tàbí ẹsẹ (*’āyah*) kan tàbí méjì pẹ̀lú rẹ̀. Nítori ẹ̀gbàwá *Ḥadīth* tí ó ní àláàfíà tí ó wá láti ọ̀dọ̀ ọmọ ’Abbās -kí Ọlọ́hun kó yọ́nú sí àwọn méjèèjì- lórí rẹ̀. Lẹ́yìn náà yóò gbé Ọlọ́hun tóbi ní ẹ̀ẹ̀kejì, yóò sì ṣe àsàlátú fún Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- bí ó ti máa ń ṣe àsàlátú níbi àtáàyá. Lẹ́yìn náà yóò gbé Ọlọ́hun tóbi ní ẹ̀ẹ̀kẹta, yóò sì wí pé:

> ***Allāhummaghfir liḥayyinā wamayyitinā washāhidinā, waghā’ibinā, waṣaghīrinā wakabīrinā, wadhakarinā wa’unthānā. Allāhumma man ’aḥyaytahu minnā fa’aḥyihi ‘alal-’Islām, waman tawaffaytahu minnā fatawaffahu ‘alal-’īmān. Allāhummaghfir lahu warḥamh, wa‘āfihi, wa‘fu ‘anh, wa’akrim nuzulah, wawassi‘ mudkhalah, waghsilhu bil-mā’i wath-thalji wal-barad, wanaqqihi minal-khaṭāyā kamā yunaqqath-thawbul-’abyaḍu minad-danas, wa’abdilhu dāran khayran min dārih, wa’ahlan khayran min ’ahlih, wa’adkhilhul-jannah, wa’a‘idhhu min ‘adhābil-qabr, wa‘adhābin-nār, wafsaḥ lahu fī qabrih, wanawwir lahu fīh. Allāhumma lā taḥrimnā ’ajrah, walā tuḍillanā ba‘dah.***
>
> **Ìrẹ Ọlọ́hun! Ṣe àforíjì fún alàáyè wa àti òkú wa; ẹni tí ń bẹ ní àáyè yìí nínú wa àti ẹni tí kò sí níbí, ọmọdé wa àti àgbàlagbà wa, ọkùnrin wa àti obìnrin wa. Ìrẹ Ọlọ́hun! Ẹnikẹ́ni tí ó bá yè nínú wa, yè é lórí ẹ̀sìn**

***Islām,*** **ẹnikẹ́ni tí ó bá sì gba ẹ̀mí rẹ̀ nínú wa, gba ẹ̀mí rẹ̀ lórí ìgbàgbọ́ òdodo. Ìrẹ Ọlọ́hun! Ṣe àforíjìn fún un; kẹ́ ẹ, fún un ní àlàáfíà, ṣe àmójúkúrò fún un, fi àpọ́nlé gbà á lálejò, jẹ́ kí ibùdésí rẹ̀ gbààyè. Wẹ̀ ẹ́ mọ́ kúrò nínú àwọn àṣìṣe rẹ̀ pẹ̀lú omi, yìnyín àti omi òjò. Sì fọ̀ ọ́ mọ́ kúrò nínú àwọn àṣìṣe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti máa ń fọ aṣọ funfun mọ́ kúrò nínú ìdọ̀tí. Fi ilé tí ó dára ju ilé rẹ̀ lọ pààrọ̀ fún un, áti ẹbí tí ó dára ju ẹbí rẹ̀ lọ, mú un wọ Ọgbà-ìdẹ̀ra, là á níbi ìyà sáréè àti ìyà iná, gbà á lááyè nínú sáréè rẹ̀, sí bá a tan ìmọ́lẹ̀ sí i. Ìrẹ Ọlọ́hun! Má ṣe dùn wá ní ẹ̀san rẹ̀, má sì sọ wá nù lẹ́yìn rẹ̀.**

Lẹ́yìn náà yóò gbé Ọlọ́hun tóbi ní ẹ̀ẹ̀kẹrin, yóò sì sálámà ní ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo sí ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ ọ̀tún.

A sì fẹ́ kí ó máa gbé ọwọ́ rẹ̀ méjèèjì sí òkè pẹ̀lú ìgbé-Ọlọ́hun tóbi kọ̀ọ̀kan. Tí òkú bá jẹ́ obìnrin, (à ó pààrọ̀ ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ *hu* sí *hā*) à ó wí pé: :“***Allāhummaghfir lahā ...*** títí dé ìparí***’’.*** Tí òkú bá jẹ́ méjì (à ó pààrọ̀ ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ *hu* sí *humā*) à ó wí pé: :“***Allāhummaghfir lahumā’’.*** Tí òkú bá sì pọ̀ à ó sọ ọ́ (ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ) di ọ̀pọ̀.

Tí ó (òkú) bá jẹ́ ọmọdé, à ó pààrọ̀ ìtọrọ àforíjìn fún un pẹ̀lú kí à wí pé:

***Allāhummaj‘alhu faraṭan, wadhukhran liwālidayh, washafī‘an mujāban. Allāhumma thaqqil bihi mawāzīnahumā wa-’a‘ẓẓim bihi ’ujūrahumā, wa’alḥiqhu biṣāliḥi salafil-mu’minīn, waj‘alhu fī kafālati Ibrāhīm ‘alayhis-salām, waqihi biraḥmatika ‘adhābal-jaḥīm.***

**Ìrẹ Ọlọ́hun! Ṣe é ní aṣáájú àti ẹ̀san àbọ̀wáábá fún àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì, tún ṣe é ní olùṣìpẹ̀ tí ìṣìpẹ̀ rẹ̀ yóò jẹ́ àtẹ́wọ́gbà. Ìrẹ Ọlọ́hun! Fi í jẹ́ kí òsùnwọ̀ àwọn méjèèjì wúwo, tún fi í jẹ́ kí ẹ̀san àwọn méjèèjì tóbi, tún mú un lépabá àwọn ẹni rere nínú àwọn asiwájú àwọn olùgbàgbọ́ òdodo. Jẹ́ kí ó wà ní abẹ́ àmójútó Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Ibrāhīm -kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a-. Là á pẹ̀lú àànú Rẹ kúrò níbi ìyà iná *Jaḥīm*.**

Ohun tí ó jẹ́ ìlànà ẹ̀sìn ni kí *Imām* dúró sí ọ̀gangan orí ọkùnrin, ààrin obìnrin, kí (òkú) ọkùnrin kángun sí *Imām* tí ó bá jẹ́ pé òkú pọ̀, kí obìnrin sì wà ni abala gábàsì. Tí àwọn ọmọdé bá wà pẹ̀lú wọn, a ó ti ọmọdékùrin síwájú obìnrin, lẹ́yìn náà obìnrin, lẹ́yìn náà

ọmọdébìnrin. Orí ọmọdékùrin yóò wà ní dèèdé orí ọkùnrin, ààrin obìnrin yóò sì wà ní dèèdé orí ọkùnrin. Bẹ́ẹ̀ náà ni ọmọdébìnrin, orí rẹ̀ yóò wà ní dèèdé orí obìnrin, ààrin rẹ̀ yóò sì wà ní dèèdé orí ọkùnrin. Gbogbo àwọn tí yóò kírun, yóò tò sí ẹ̀yìn *Imām* àyàfi tí ó bá jẹ́ ẹnìkan tí kò sì rí ààyè ní ẹ̀yìn *Imām,* òun yóò dúró sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún rẹ̀.

Gbogbo ọpẹ́ àti ẹyìn ti Ọlọ́hun Allāh nìkan ṣoṣo ni í ṣe. Àti pé kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlà Rẹ̀ máa bá Òjíṣẹ́ Rẹ̀ Muḥammad, àwọn ẹbí rẹ̀ àti àwọn sàábé rẹ̀.